# IDAJỌ NIPA YÌNYÍN, EÉṢÚ ATI ÒKÙNKÙN

## Ẹksodu 9:13-35; 10:1-29

## ẸKỌ 55 -- AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "OLUWA ti ipò rẹ̀ jade lati bẹ̀ aiṣedede ẹniti ngbe ori ilẹ wo lori ilẹ" (Isaiah 26:21).**

**A Fun Wọn ni Anfaani Aabo**

Ipọnju nla miiran n bọ wa fun awọn ara Egipti, ju eyi ti wọn ti ri nipa arun mẹfa ti o ti kọja. Awọn wọnyii ti n bọ wa yoo mù wọ́n lomi de gongo ọkàn. Ṣugbọn aanu dapọ mọ́ idajọ yii.

Ọlọrun sọ fun Mose lati sọ fun Farao pe Oun yoo rán yinyin nla eyi ti o tobi ju ohunkohun ti o ti i ṣẹlẹ ni ilẹ naa ri lọ. Yoo buru to bẹẹ gẹẹ ti awọn eniyan ti o wà lode yoo fi kú, nitori bẹẹ, Mose kilọ fun ọba lati mu gbogbo awọn iranṣẹ ati gbogbo agbo-ẹran rẹ̀ kuro loko. Lẹyin gbogbo ibanujẹ ti Ọlọrun ti mu wá sori awọn ara Egipti, a le ro pe awọn eniyan naa yoo gba ohun ti Mose ti sọ tẹlẹ gbọ́ kiakia pe yoo ṣẹ, wọn o si sá sabẹ aabo. Ṣugbọn awọn kan kò bẹru Oluwa, wọn duro ninu odo si pa wọn pẹlu gbogbo agbo-ẹran ti kò si ninu abà. Iwọ ko ha ni ro pe awọn eniyan bawọnyii jẹ́ aṣiwere lati duro lode ki a fi pa wọn?

Jesu ti kilọ fun wa pe ọjọ ibinu Oun n bọ̀, awọn ti o ba si n fẹ igbala le wá sọdọ Rẹ̀ ki a le daabo bo wọn labẹ Ẹjẹ Rẹ̀. Ṣugbọn awọn eniyan n ba ọna aibikita wọn lọ lai mọ wakati ti idajọ yoo sọkalẹ, sibẹ wọn ko mura silẹ lati pade Ọlọrun. Oluwa le de nigbakugba; nigba naa awọn ti o ti ṣe tan yoo goke lọ ipade Rẹ̀, awọn ti o ba si kù lẹyin yoo ni lati la ipọnju nla ni kọja. Jesu wi pe ẹni meji yoo sùn lori akete kan; a oo mu ọ̀kan a oo si fi ekeji silẹ. Obinrin meji yoo maa lọ ọlọ; a oo mu ọ̀kan a oo si fi ekeji silẹ. Bawo ni yoo ti buru to bi o ba ṣe pe iwọ ni a fi silẹ? Ẹmi Ọlọrun wi pe "ẹnikẹni o ba fẹ" le wá, eyi ni nì pe gbogbo eniyan.

Ọlọrun ti fi Farao jọba, O si ti fun un ni agbara nla. Ki i ṣe ifẹ Ọlọrun pe ki Farao ṣègbé; ṣugbọn bi oun yoo ba dojuja kọ Ọlọrun ki o si kọ̀ jalẹ, Oluwa fẹ ki gbogbo aye ki o mọ ohun ti yoo ṣẹlẹ si iru eniyan bẹẹ. Bi agbara rẹ̀ ti ga to bẹẹ naa ni iṣubu rẹ̀ yoo ti tobi to. Ọlọrun fẹ ki o di mimọ̀ pe Oun ni Oluwa gbogbo agbaye.

Lati ọdun pupọ ni awọn eniyan ti gbiyanju lati wi pe arun wọnyii kò wa sori Egipti ri; ṣugbọn lai pẹ yii awọn ọjọgbọn walẹ̀walẹ̀ ti ri awọn ohun ti a kọ sara okuta ti wọn wà jade lati abẹ ilẹ wá, ti n sọ nipa ti iparun awamaridi ni Egipti, ati ti ijadelọ ogunlọgọ awọn Heberu ẹrú. Ọrọ Ọlọrun duro ṣinṣin laaarin atako awọn alaigbagbọ́ lati ayebaye, ohun ti O si ti wi yoo ṣẹ dandan.

**Yinyin, Aara, ati Manamana**

Nigba ti Mose na ọpa rẹ̀ jade yinyin bẹrẹ si i já bọ́, aara sán kikankikan, manamana kọ, iná si n là kaakiri ilẹ. Ọpọ eniyan ni o maa n gbadura nigba ti wọn ba gbọ iro aara, bẹẹ ni o si yẹ ki wọn ṣe, nitori manamana le lu wọn pa nigbakugba. Ṣugbọn ironupiwada ti o tipa ibẹru wá ki i pẹ́ lọ titi. Nigba ti iji naa ba kọja ti ibẹru si kuro, adura wọnni a di igbagbe.

Yinyin wọnni tobi to bẹẹ ti wọn fi ba eso oko jẹ́, awọn igi pẹlu wó lulẹ, awọn eniyan ati ẹran-ọsin ti kò si labẹ aabo si kú pẹlu. Ṣugbọn kò si iji ni Goṣeni. Boya awọn Ọmọ Israẹli gbọ aara wọn si mọ̀ wahala ti o n lọ ni Egipti; boya wọn ri manamanna pẹlu, ṣugbọn ọmọ Ọlọrun ni wọn i ṣe, wọn si wà labẹ aabo Rẹ̀. Kò si manamana kankan ni Goṣeni kò si yinyin ti o bọ́ si oko awọn Heberu.

**Abamọ Ti Kò Ni Ironupiwada**

Farao bẹrẹ si i ri imọlẹ. O gba pe ẹlẹṣẹ ni oun i ṣe, o si bẹ Mose ki o gbadura fun oun. Ṣugbọn sibẹ ko wi pe oun kaanu fun awọn ẹ̀ṣẹ oun. O dabi awọn eniyan ti o kaanu pe ẹ̀ṣẹ wọn kó wọn sinu wahala, ṣugbọn ti wọn kò kaanu pe awọn ti ṣẹ̀ si Ọlọrun.

Mose jade kuro niwaju Farao, o na ọwọ́ rẹ̀ soju ọrun, iji naa si dakẹ. Ṣugbọn wo adanu ti o ti ṣẹlẹ! Gbogbo awọn ohun ọgbin ti wọn i ba kore ni o ti parun; gbogbo igi ti wó lulẹ; ọpọlọpọ eniyan ni o si ti kú. Lẹsẹ kan naa ti ọba ri i pe iji ká kuro, o gbagbe ijẹwọ ẹ̀ṣẹ rẹ, o si n dá ẹ̀ṣẹ lọ si i.

**Igboya Mimọ́**

Mose tubọ n beere ohun ti o fẹ kikankikan. Oun kò bẹru Farao (o si ya ni lẹnu pe ọba kò tilẹ daba ati pa Mose ati Aarọni), ṣugbọn o fi igboya duro niwaju rẹ̀ o si sọ fun un pe arun miiran n bọ wa ba a. Ẹmi Ọlọrun ninu ọkàn awọn eniyan Rẹ̀ maa n fun wọn ni igboya lati dojuja kọ ẹ̀ṣẹ ati agbara okunkun. A kà nipa igboya Daniẹli nigba ti wọn n halẹ pe wọn yoo sọ ọ sinu iho kiniun. O gbadura gẹgẹ bi iṣe rẹ̀ o si gbẹkẹle Ọlọrun lati pa oun mọ́. Awọn ọmọ Heberu mẹta wọnni le wi pe "Kò tọ si wa lati fi èsi kan fun ọ nitori ọ̀ran yi. Bi o ba ri bẽ, Ọlọrun wa ti awa nsìn, le gbà wa lọwọ iná ileru na ti njo, on o si gbà wa lọwọ rẹ, ọba. Ṣugbọn bi bẽkọ, ki o ye ọ, ọba pe, awa ki yio sin oriṣa rẹ" (Daniẹli 3:16-18).

**Ebi N Bọ̀**

Igba tubọ n le si i ni Egipti. Nigba diẹ si i ko ni si ounjẹ mọ́ lati jẹ. Yinyin ti pa ohun ọgbin pupọ run, nisisiyii a sọ pe eeṣu yoo wá, wọn yoo si jẹ ohun gbogbo ti o kù silẹ. Ara awọn iranṣẹ Farao ko le gbà a mọ. Ọba kò ha ri i pe a n pa ilẹ wọn run? Ki ni anfaani gbogbo awọn ẹrú naa bi kò ba si nnkan kan lati jẹ? Ki ni ṣe ti a kò fi jẹ ki awọn eniyan naa lọ ki alaafia ati idẹra ba le tun wa laaarin ilu?

Farao gba ohun ti wọn wi rò, o si pe Mose ati Aaroni wá iwaju rẹ̀. O wi fun wọn pe ki wọn tun sọ ohun ti awọn n fẹ ṣe gan an, bi o tilẹ jẹ pe o da wa loju pe o ti mọ ọn. O rò pe boya nisisiyii Mose yoo gbojẹgẹ ki o má si beere

ohun ti o le lo bẹẹ mọ. Ṣugbọn Mose kò jẹ juwọ silẹ rara. Wọn ni lati mu ohun gbogbo ti wọn ni lọwọ nigba ti wọn ba n lọ sin Ọlọrun gẹgẹ bi a ti ni lati fi ohun gbogbo ti a ni rubọ ki a ba le wu Olugbala. Mose taku pe gbogbo wọn ni yoo jumọ lọ si aginju lati jọsin; ati ewe ati agba, ọkunrin ati obinrin, agbo-agutan ati ọ̀wọ́-ẹran. Farao sé aya rẹ̀ le sibẹ; nitori bẹẹ, Mose si na ọwọ rẹ̀ sori ilẹ, awọn eeṣu si jade wá

Nibi gbogbo ni awọn eeṣu naa wà. Wọn gbalẹ kan to bẹẹ gẹẹ ti awọn eniyan kò fi le rin lai tẹ̀ wọn mọlẹ. Awọn eeṣu wọnyii wa sinu gbogbo ilẹ; wọn kun oju-ọrun titi wọn fi dabi ikuuku loju awọsanma. Wọn jẹ gbogbo ewebẹ ti yinyin kò parun.

Farao ri i pe bi wahala yii kò ba duro yoo yọri si ikú gbogbo wọn, nitori bẹẹ o yara ranṣẹ si Mose ati Aaroni lẹẹkan si i. O jẹwọ pe oun ti dẹ́ṣẹ̀ si Ọlọrun ati si Mose, ṣugbọn kò wi pe oun kaanu fun ẹ̀ṣẹ oun. O kàn n fẹ ki a dariji oun ṣá ki oun má ba kú. Nigba ti Ọlọrun mu awọn eeṣu naa kuro Oun kò fi ikankan silẹ lati bajẹ si oko, ṣugbọn O gbá wọn lọ patapata sinu Okun Pupa – lai ku kan. Sibẹ Farao kò jẹ ki awọn eniyan wọnyii lọ.

**Okunkun Biribiri**

Mose kò kilọ fun ọba nipa arun miiran ti o n bọ wa. Ni igbọran si aṣẹ Ọlọrun o na ọwọ rẹ̀ jade okunkun si bo ilẹ naa. Ni atetekọṣe Ọlọrun wi pe, "Ki imọlẹ ki o wà," imọlẹ si wà. Ọlọrun Ọrun lai ṣe awọn ọlọrun ti awọn ara Egipti n sin ni o ni aṣẹ lori imọlẹ ati okunkun. Lẹyin ọlọrun oorun ati ọlọrun imọlẹ ti awọn ara Egipti gbagbọ́, wọn ni ọlọrun iná pẹlu, eyi ti arun okunkun sọ di alailagbara. O dabi ẹni pe ni akoko okunkun yii iná atọwọda paapaa ko le mọlẹ. Awọn eniyan ko le jade nile wọn fun ọjọ mẹta nitori wọn ko le ri ohunkohun. Okunkun ṣú to bẹẹ ti wọn fẹrẹ le fi ọwọ kan an. Ṣugbọn gbogbo awọn ọmọ Israẹli li o ni imọlẹ ni ibugbé wọn" (Ẹksodu 10:23). Iwọ kò ha ni fẹ lati wà ni ile kekere kan ni Goṣeni nibi ti imọlẹ wà, ju lati wa ni aafin daradara Farao nibi ti o ṣokunkun biribiri? Iyà ọjọ mẹta pere ni awọn ara Egipti jẹ ninu okunkun yii, ṣugbọn awọn ẹlẹṣẹ ti wọn n yi pada kuro lọdọ Ọlọrun bayii ti wọn si kọ̀ lati ronupiwada, ati awọn ara Egipti wọnni n bọ wa gbọ idajọ Ọlọrun pe: "Ẹ di i tọwọ tẹsẹ, ẹ gbé e kuro, ki ẹ si sọ ọ sinu òkunkun lode; nibẹ̀ li ẹkún on ipahinkeke yio gbé wà" (Matteu 22:13). Okunkun naa yoo wa bẹẹ titi lae lai ni opin.

Ọna Onigbagbọ ti dara ju bẹẹ lọ to! "Ipa-ọ̀na awọn olõtọ dabi titàn imọlẹ, ti o ntàn siwaju ati siwaju titi di ọsangangan" (Owe 4:18). Imọlẹ ayé ni Jesu jẹ́ nisisiyii, nigba ti a ba si de Ọrun a oo ri i pe a kò fẹ oorun tabi oṣupa, nitori ogo Ọlọrun yoo tan imọlẹ si i, ati pe "Ọdọ-Agutan si ni fitila rẹ̀" (Ifihan 21:23). Ko si ẹni kan ti yoo bẹru okunkun mọ́.

**Yọnda fun Igba Diẹ**

Lẹẹkan si i Farao gbà lati jẹ ki awọn eniyan naa lọ -- ani pẹlu awọn ọmọ wẹẹrẹ lakoko yii. Ṣugbọn sibẹ, o n fẹ ki wọn fi agbo-ẹran ati ọ̀wọ-ẹran wọn silẹ. Mose ko jẹ gba bẹẹ. Ohun gbogbo ni o gbọdọ lọ! Ọlọrun ti paṣẹ bẹẹ; ati paapaa bi wọn ba lọ si aginju pẹlu iba obukọ diẹ lati fi rubọ si Oluwa, ki ni yoo ṣẹlẹ bi Ọlọrun ba beere agutan? Tabi bi wọn ba mu agutan diẹ lọwọ, Ọlọrun le beere maluu. Paapaa pẹlu, ogunlọgọ eniyan wọnyii yoo ni lati ni ohun ti wọn o jẹ nigba ti wọn ba wà ni aginju.

Ibeere Mose mu ki inu bi Farao to bẹẹ ti o fi wi fun un pe ki o maa lọ ki o ma si tun wá siwaju oun mọ́. Mose gbà lati fi Farao silẹ, lati má tun pada mọ, ṣugbọn ki o to lọ o fun ọba ni ikilọ ikẹyin rẹ̀, nipa ikú gbogbo akọbi wọn.

**AWỌN IBEERE**

1. Bawo ni a ṣe fi aanu hàn fun awọn ara Egipti ninu arun keje? Njẹ gbogbo wọn ni o tẹwọ gbà a? Ki ni ṣẹlẹ si awọn ti kò gbà á?
2. Bawo ni a ṣe le bọ́ lọwọ idajọ Ọlọrun?
3. Njẹ Mose bẹru Farao? Ki ni ṣe ti kò fi bẹru?
4. Bawo ni a ti lè fi fun Ọlọrun pọ̀ to nigba ti a ba n sin In?
5. Bawo ni o ti ṣokunkun to ni Egipti ni akoko arun kẹsan-an? Njẹ okunkun ṣú ni Goṣeni?